# PẸPẸ IDẸ: APẸẸRẸ IDALARE

**Ẹksodu 27:1-8; 38:1-7; 40:28-32; Lefitiku 6:1-7; 7:1-7**

**ẸKỌ 72 FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Laisi itajẹsilẹ kò si idariji" (Heberu 9:22).**

### Irin Ajo Lọ si Agọ

Ẹ jẹ ki a fi oju ẹmi wò o pe a wà ni aginju Sinai, a n lọ gẹgẹ bi awọn Ọmọ Israẹli sinu Agọ lati lọ rubọ fun ẹ̀ṣẹ wa. A pa Agọ yii gẹgẹ bi aṣẹ ti Ọlọrun fun Mose lori oke; nigba ti awọn alufa si gbe ẹbọ sori pẹpẹ, ina iyanu bọ́ sori rẹ lati Ọrun wa, o si jo o. Ina yii kò si gbọdọ kú.

A rin kaakiri laaarin agọ́ awọn ọmọ Lefi, ti a kọ́ yi Agọ́ ti o wà laaarin ibudo ká. A oo wọle lati iha ila oorun nitori ẹnu ọna kan ṣoṣo ni o wọ agbala ti o yi Agọ ká. Ibikibi ti a ba pa Agọ si ninu aginju laaarin igba ti awọn Ọmọ Israẹli n rin kaakiri, ẹnu ọna rẹ gbọdọ kọju si iha ila oorun.

### Agbala Agọ

A wọ inu agbala Agọ naa. Nihin yii ni a ti n ṣe isin ti gbogbo-gbo. Ko si ẹni kan ti o gbọdọ kọja agbala yii bi kò ṣe awọn alufaa. Niwaju wa ni a ri pẹpẹ idẹ, ti o dọgba ni igun mẹrẹẹrin, iwo si wa ni igun kọọkan. Idẹ jẹ apẹẹrẹ idajọ; pẹpẹ yii ati gbogbo ohun-elo ti a n lo nihin jẹ ti idẹ.

Ọlọrun a maa dá ẹ̀ṣẹ lẹbi, ati ni ọjọ idajọ, olukuluku ẹni ti o ba ni ẹṣẹ ni igbesi aye rẹ yoo jiya iku keji. Aṣẹ Ọlọrun ni pe ki a ta ẹjẹ silẹ lati bo ẹṣẹ eniyan mọlẹ, ẹṣẹ kekere ati ẹṣẹ nla. Gbogbo ẹṣẹ -- ríré Ofin kọja, ni yoo gba idajọ Ọlọrun; ẹlẹṣẹ naa yoo si ṣegbe, bi oun kò ba gba ọna igbala Ọlọrun.

### Ọdọ-Agutan, Arọpo Wa

A mu ọdọ-agutan pipe, ọdọ-agutan ti kò labuku wá lati fi rubọ si Ọlọrun bi ẹbọ irekọja fun ẹṣẹ wa. O jẹ ẹbọ ààye, eyi ti o jẹ apẹẹrẹ pe a fi ara wa rubọ fun Oluwa. Awọn miiran ṣe alaini to bẹẹ ti wọn kò le mu ọdọ-agutan tabi agbò wa, ṣugbọn ireti wa fun awọn naa, pẹlu. Ọlọrun ti ṣe eto pe ki wọn mu adaba meji tabi ẹyẹle meji wá. A kò gbọdọ fi idalare du ẹnikẹni rara.

A wa siwaju alufaa pẹlu ọdọ-agutan wa, o si sọ ohun ti a ni lati ṣe fun wa. A kọju si Ibi Mimọ nibi ti oju Ọlọrun wà, a o si ronu pe, "Mo kó gbogbo ẹ̀ṣẹ mi le ọ. Mo ti ṣẹ. O ṣe mi laanu pe mo ti ba Ọlọrun ninu jẹ́. Mo yẹ si iku, ṣugbọn Ọlọrun wi pe, iwọ, ọdọ-agutan kekere yii le kú ni ipò mi." Bawo ni inu wa ti dun to pe Ọlọrun fẹ gba ọdọ-agutan naa dipo wa!

### A Ta Ẹjẹ Silẹ

A pa ọdọ-agutan yii. Alufaa gba ẹjẹ rẹ sinu awo koto, o si fi wọ́n pẹpẹ. A ti jẹwọ ẹṣẹ wa niwaju alufaa, ti i ṣe aṣoju Ọlọrun, a ti ronupiwada ẹṣẹ wa a si ti mu ẹbọ fun etutu wá. Alufaa ti gba arọpo wa, a si ti pa ọdọ-agutan naa dipo wa. Ọlọrun ri ẹjẹ naa ati igbagbọ wa, inu Rẹ̀ si dun si wa; a si dariji wa nipa wiwo ọjọ iwaju pẹlu igbagbọ́, fun Jesu ti yoo wá kú gẹgẹ bi Ọdọ-Agutan Ọlọrun.

### Jesu Ọdọ-Agutan Wa

Nisisiyii ẹ jẹ ki a ro ohun ti a le ṣe ni akoko ti wa lonii, ki a ba le gbà wa là. Ọlọrun korira ẹṣẹ sibẹ, O si n dá olukuluku ẹni ti o bá ni ẹṣẹ lookan aya rẹ lẹbi ikú. Mimọ́ ni Ọlọrun, a ko si le sunmọ ọdọ Rẹ̀ pẹlu ẹṣẹ ni igbesi-ayé wa. Ẹjẹ Jesu gbọdọ bo ẹṣẹ wa mọlẹ, lati pa a mọ́ kuro loju Ọlọrun, nitori "laisi itajẹsilẹ kò si idariji" (Heberu 9:22).

Ki ni ohun ti o yẹ ki a ṣe? Ọlọrun kò fẹ ki a pa ọdọ-agutan mọ́, nitori wọn jẹ apẹẹrẹ Jesu – Jesu si ti wá. Ki ni Jesu ṣe lati ràn wa lọwọ nigba ti O wà ninu aye? O ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ lati fi bo ẹṣẹ wa mọlẹ, gẹgẹ bi awọn ọdọ-agutan ti a n pa ninu Agọ́ ti jẹ apẹẹrẹ ohun ti Oun yoo ṣe. Jesu wi pe: "Nitori eyi li ẹ̀jẹ mi ti majẹmu titun, ti a ta silẹ fun ọ̀pọ enia fun imukuro ẹ̀ṣẹ" (Matteu 26:28). Njẹ inu wa kò dun pe ireti wà fun wa nipasẹ Ẹjẹ ti Jesu ta silẹ?

### Ijiya Kristi

A ranti bi ọdọ-agutan kekere naa ti jiya ti o si kú nitori awọn Ọmọ Israẹli dẹ́ṣẹ̀, ọdọ-agutan kan fun ẹṣẹ eniyan kan; ṣugbọn ro o bi Ọmọ Ọlọrun Ayeraye ti jiya nigba ti O fi ara Rẹ̀ rubọ gẹgẹ bi Ọdọ-agutan, ti O si rù ẹṣẹ gbogbo agbaye. "Bẽni Kristi pẹlu lẹhin ti a ti fi rubọ lẽkanṣoṣo lati ru ẹ̀ṣẹ ọ̀pọlọpọ" (Heberu 9:28). "Gbogbo wa ti ṣina kirikiri bi agutan; … OLUWA si ti mu aiṣedede wa gbogbo pade lara rẹ̀" (Isaiah 53:6). Rò gbogbo ijiya Jesu ninu ọgbà nì ki a to kàn An mọ agbelebu, nigba ti O mọ bi ẹru naa ti wuwo to; ati lẹyin naa iru iku ibanujẹ ti O kú lori agbelebu. Ṣugbọn tifẹtifẹ ni O fi la irora nlá nlà naa kọja ki a ba le gba iwọ ati emi là. Nigba ti Jesu san igbese nlá nlà bayii, ki Ẹjẹ Rẹ̀ ba le wà fun irapada wa, njẹ kò ha yẹ ki a yara lati gba Ẹjẹ naa sinu ọkàn wa ki a ba le ni anfaani lati ri idariji ẹ̀ṣẹ wa gbà?

Awọn miiran ko ka ẹṣẹ si nnkan ti o buru pupọ. Wọn rò pe wọn le jẹ Onigbagbọ́ ki wọn si ni ẹṣẹ ni igbesi aye wọn sibẹ. Ọlọrun fẹran Ọmọ Rẹ̀ kan ṣoṣo ju bi awa ṣe le fẹran awọn ọmọ wa, sibẹ pẹlu ifẹ ni O fi gba pe ki Olugbala

jiya iku oro bẹ́ẹ̀ lati mu ẹṣẹ wa kuro.  Ni wakati naa gan an ti Jesu rù ẹṣẹ gbogbo agbaye lori agbelebu, Ọlọrun yí oju Rẹ̀ kuro nitori O korira ẹṣẹ.  Njẹ iwọ rò pe Ọlọrun le fara da ẹṣẹ ni igbesi aye eniyan lai da a lẹbi ikú?

**Jesu Alufaa Wa**

Awọn alufaa wà ninu Agọ ti wọn n fi ọdọ-agutan rubọ.  Ta ni fi Jesu rubọ?  Oun ni O fi ara Rẹ̀ rubọ.  Jesu ni Ọdọ-agutan naa, Oun si ni Alufaa pẹlu.  Sibẹ Oun tun ni Olori Alufaa wa ni Ọrun, O n fi àpá ọgbẹ́ ti O gbà han Baba ki O le bo ẹṣẹ wa mọlẹ.  "Bi Kristi pẹlu ti fẹ wa, ti o si fi ara rẹ̀ fun wa li ọrẹ ati ẹbọ fun Ọlọrun fun õrùn didun" (Efesu 5:2).

**Jesu ni Ọna**

A ti kọ́ ẹkọ pe Agọ ati ohun gbogbo ti o wà ninu rẹ jẹ apẹẹrẹ eto igbala Ọlọrun fun wa.  Oju ọ̀na kan ṣoṣo ni o wà nibẹ, abawọle ti o wa ni apa iha ilà oorun.  Njẹ o ri ohun ti eyi n tọka si?  Jesu wi pe: "Emi ni ilẹkun: bi ẹnikan ba ba ọdọ mi wọle, on li a o gbà là" (Johannu 10:9).  O wi pe ole ati ọlọṣa ni ẹni ti o n gbiyanju lati gba ọna miiran wọ Ọrun.  O daju pe a kò ni fẹ ki Jesu pe wa ni ole, nitori bẹẹ a ni lati wọle gẹgẹ bi Ọrọ Rẹ̀ ti paṣẹ fun wa: "Bi awa ba jẹwọ ẹ̀ṣẹ wa, olõtọ ati olododo li on lati dari ẹṣẹ wa jì wa, ati lati wẹ̀ wa nù kuro ninu aiṣododo gbogbo" (1 Johannu 1:9).  "Jẹ ki enia buburu kọ̀ ọ̀na rẹ̀ silẹ, ki ẹ̀lẹṣẹ si kọ̀ ironu rẹ silẹ; si jẹ ki o yipada si OLUWA, on o si ṣãnu fun u, ati si Ọlọrun wa, yio si fi jì li ọpọlọpọ" (Isaiah 55:7).

**Idalare nipa Ẹjẹ Jesu**

Bayi ni a ri i pe awa paapaa, lọjọ oni, gbọdọ ṣe ju pe ki a gba Kristi gbọ́ nipa èro orí lasan lọ.  A gbọdọ ronupiwada ẹ̀ṣẹ wa, ki a kọ ọ silẹ, ki a si bẹ Jesu pe ki O fi Ẹjẹ Rẹ̀ bò wọn mọlẹ, ki a si gbagbọ pe O ti dariji wa.  Nigba naa ni a dá wa lare niwaju Ọlọrun, ati pe "Ẹmí tikararẹ̀ li o mba ẹmí wa jẹrí pe ọmọ Ọlọrun li awa iṣe" (Romu 8:16); a oo ni agbara maa lọ, má dẹṣẹ mọ́.

Ọlọrun wi pe kiku ni ẹlẹṣẹ yoo kú, ṣugbọn Jesu ti sọ pe "Njẹ emi ko ha le ku dipo rẹ̀?"  Ọlọrun fẹran Ọmọ Rẹ̀, O si ba A ninu jẹ lati ri i pe O jiya; ṣugbọn Ọlọrun fẹran awa eniyan pẹlu, nitori naa O sọ fun Jesu pe, O le lọ ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ fun wa.  Lonii, Jesu duro gẹgẹ bi Olori Alufaa wa niwaju Ọlọrun, O n fi Ẹjẹ iyebiye nì han An lati rán Onidajọ aye leti pe Oun ti san owo irapada wa.

## AWỌN IBEERE

1. Bawo ni Ọmọ Israẹli kan ṣe le ri idariji ẹṣẹ rẹ̀ gbà?
2. Ki ni ẹbọ ti o mú wa?
3. Nibo ni pẹpẹ idẹ wà?
4. Ki ni a ni lati ṣe ki a to le gbà wá là?
5. Bawo ni a ṣe le mọ pe a ti gba wa là?
6. Ki ni owo irapada wa?